COMPLIMENTARY COPY

**Akiyesi**

A nfẹ Ẹniti yio ma ba wa ta Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbegbe Ilorin tabi Ilu miran. E kọwe si ọdọ Ọgbẹni: R. O. Adedeji Esq. Ni P. O. Box 12 Ilorin

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Wanted**

APPRENTICE-PRINTERS.

APPPLY MANAGER

6, Ojo Road, Odu-Alẹrẹ, Mushin

VOL. III No. 146 — MONDAY MAY 2 — MAY 8 1960 — KỌBỌ KAN (1d)

# Eleri di eniti awon Olopa nfa Digbadigba ti won si lo Timole

ENUGU:- ẸLẸRI KAN NIHIN NIBI ETO IWADI IWA IGARA, OLE, ATI ILỌNI-LỌWỌ GBA TI IJỌBA IPINLẸ ILA ORUN YAN LATI ṢE IWADI IWA WỌNYI TI WỌN NI AWỌN ỌMỌ ILE IGBIMỌ IBILẸ ENUGU NHU TI ALAGA RẸ SI JẸ ỌGBẸNI PERKINS NI AWỌN ỌLỌPA MU NIHIN LẸHIN IGBATI O TI JẸRI TAN TI ALAGBA ETO IWADI SI PA LAṢẸ PE KI WỌN MU.

Alaga sọ wipe ẹri eke ni Ọgbẹni na Albert Izuzue ti ọn ni ki awọn Ọlọpa mu yi wa jẹ, atipe alagabagebe enia lo nṣe, kaka ki o dahun ibere kẹ niṣe ni o nfi ọrọ si abẹ ahọn sọ, alaga Ọgbẹni Perkins ni nitori idi eyi ni on ṣe ni ki wọn mu Ọgbẹni Albert Izuzue na.

Ọgbẹni Perkins tun ṣe afikun pe niṣe ni Albert tun mọmọ purọ niwaju on, o wa paṣẹ fun awọn Ọlọpa pe ki wọn mu lọ lati le gba ọrọ ẹnu rẹ silẹ.

Albert lo fi ọwọ ara rẹ fa sababi ati adewaba ti o ba a, idi re re. Nigbati eto iwadi iwa raunraun yi bẹ rẹ funrẹ lo lọ fi ọwọ si iwe pe on fẹ jẹri niwaju iwadi yi, lẹhin igbayẹn lo ṣẹṣẹ wa kọ pe on ko fẹ jẹrimọ Alaga iwadi na Ọgbẹni Perkins wa ṣe iwe imuni nipa wọn si lọ fi iwe yi gbe Albert Izuzue, Alaga nọ sọ fun u pe o gbọdọ ma ti agọ Ọlọpa wa sibi Iwadi yi.

Ọgbẹni Albert Izuzue si wa nikawọ awọn Ọlọpa o si ti sọrọ fun wọn ṣugbọn a ko mọ ohun ti o sọ, ṣugbọn ọkan da wa loju pe wọn o gbe ẹjọ rẹ lọ si ile ẹjọ lati wadi gẹgẹ bi ọrọ rẹ ti ri.

## Padi Aguda jebi ni Kotu

Bamenda:- Ẹni ọwọ Nicholas V. Bildebeck ẹni 79 ni ile ẹjọ nihin ni ko lọ san pọun mẹta tabi ko lọ si ẹwọn oṣu kan nigbati o gba pe on jẹbi pe on na ọdọ mọbirin kan ọmọ ọdun mọkan dinlogun ti orukọ rẹ njẹ Mary V Vikpuh ninu sọṣi ni ọjọ kejila oṣu April.

Lẹhin igbati o ti gba pe on na ọmọ birin yi ni kotu, adajọ pa laṣẹ fun pe ki o lọ san pọun meji fun ọdọmọ-

WO OJU EWE KẸRIN

## Ha! etı re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata to dara ju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹ ri lọ, lẹhin ata lilọ, o tun le lọ Igbado ati Ọka-Baba, at Ewa-ere orişirişi.

**£45 ni a nta** Pelu Ẹnjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Elẹtiriki Mutọ.

O WA NI ṢỌBU

**Akoshile Brothers**

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599
Phone No. 24395. Lagos

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pa taki ta ṣe ni Aṣẹpe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idanilojo fun Awọn Iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi j ẹ d i Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan mitan bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde, osi njẹki awọn ọmọde lobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti koṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti ẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

**LILO RE:-** Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributers*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria, Phone 22515

34, Docemo Street, Lagos, Phone 204247

**IMOLE**

ESIN ORO WA-
IMOLE DE OKUNKUN
PARADA
Editorial Works & Office
16, Bmgbose Street,
Lagos
Telephone:- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,

## E wadi oro yi wo

Loju awa oniwe Irohin Imole: o dabi eni wipe owo yepere ni awon omo egbe asofin ti N.C.N.C ni Igbimo apapo fe fi mu oro ti ojogbon ninu isiro Dokita Chike Obi so ninu ile Igbimo ati ni ajo ipade awon oniwe Irohin wipe nise ni awon kan ninu awon Alase Ijoba ati awon omo ile igbimo pa-apa nlu awon mekunu ilu je.

Dokita Obi so yi ki i se oro yepere rara, nitoripe o fi idi han gbangba pe oto oro ni oro ti on nso sugbon kaka ki awon ti Chike Obi nfi esun kan ki won dahuu wipe ko si otito ninu oro ti o so nise ni won fi eyi ti o ye si le fun won lati se lai se won wa nse eyi ti ko to fun won lati se, loro kan gegebi owe yoruba, won fi ete sile lai pa won npa lapalapa.

Dokita Obi fi esun igara, ole, ati jibiti kan awon alase Ijoba ni pataki julo olori omo egbe asofin ti N.C.N.C. ti o tun je alase eto inawo Ijoba kaka ki won dahun esun yi, nise ni won nso kabakaba,

ti won nwi koboraja. ti won wa so wipe awon gbe Dokita Obi lo si ijoko ehin, lehinna awon tun ro loye egbe awon, a nwi iru, won nwi iru, a ni ole ni o, o ni rara o, omo eran ke re lo lo gbe loja.

A ti fi esun kan o, kaka ki o dahun pe o ko se ohun ti a ka si o lese o ni o ti o eniti o fi sun e ni ori re ko pe

Gbogbo mekunu ilu, ko fe mo bi asiwere ni Dokita Obi, oro ti o so ni a fe ki e fi eti si, lai fi eti si ko si ohun ti e le se fun u, ti o le pa otito re, otito leke. Gbogbo enia ti mo pe ninu gbogbo yin ko si eyi ti o ro ti mekunu si ire a fi ti apo won nikan ni. Ohun Dokita Obi nikan ni ohun mekunu e ba pe ni asiwere o, tabi asiwin tabi oruko koruko on si ni wura ati ohun mekunu.

Eyiti imu ba erun ninu yin kio lo se dede oro Obi je oro ti e gbodo wadi, ki i se oro ti e gbodo mu ye pere rara o, E wadi se.

## Ija sele ni Onitsha nitori Mosalasi

A gbo irohin wipe edekoyede kan be sile larin awon Musulumi Onitsha ati Okunrin kan ti a npe ni Alhaji Yusawu ohun ti a gbo pe o fa ede koyede na wa ni wipe, awon Musulumi Onitsha so pe Mosalasi Jimo won kere, nitorina awon fe dawo ki nwon tunko ki o tobi.

Ibe ni Alhaji Yusawu ti dahun pe nwon ba efon labata' nwon yoobe tii nwon sebi omi lo mu ku sile, tabi won ko mo pe enikan lo ni Mosalasi na ni ndan?

Awon Joma Musulumi dahun pe, awon Imale Onitsha lo ni Mosalasi na, ko nse ogun enikan, Alhaji Yusawu wa pase pe enikeni ko gbodo tun ile no ko.

Nigbana ni, awon Musulumi wa lo pe lejo Alhaji naro ejo tire o si jare won ,Adajo da a lare, o ni ki awon Musulumi le sanwo itin ese fun u, adosan le mejo poun ati sile mewa igba na wa ni awon Musulumi Onitsha ti lo so agbeje medi.

## Oyinbo Ajoji kan sese de ti o nje Pepsi-Cola

Irohin kan wa lara nibiti o gbe doso wipe awon oyinbo ajeji kan sese de lati ilu Amerika si Ibadan lati wa ona gegebi nwon o ti se le ma se ogbin ohun kan ti nwon npe ni pepsi-cola, bi oro ba dogba po pelu awon egbe Western Nigeria Development corporation wiwa ti nwon wa ote yi ni lati mu adehun na de opin nipa dida orisi pepsi-cola merin sile nile Nigeria.

Orisi meji yio wa ni Mushin ati Ibadan, orisi meji ti o ku yio wa ni Onitsha ati Kano.

Ogbeni Rewane ti ise alaga igbimo Western Nigeria Development corporation lo lo fi apa ibiti nwon o se ogbin pepsi-cola na si ni agbegbe Ibadan han.

## Awon Oyinbo South-Africa tun de o!

NI OWURO ojo Jimoh to koja lo yi ni awon Oyinbo apa isale Afrika (South Africa) ko awon Soja bi iwon egberun, nwon lo fi mo odi yi Ilu Tanga ka ni biti awon Enia dudu ngbe, nwon wa de awon Olopa si arin Ilu pelu Kumo, Kondo, ati ohun ija, nwon si bere si ko awon ti o je Gbajumo ati enia pataki lo si Itimole. Ohun ti o mu won se be ni pe ni ilu Langa ni awon enia pataki ti nwon nta korogbon si Ijoba, gbe wa, iye awon enia ti Olopa ri ko ni Ilu na to ogoji le-lodunrun enia.

Ohun ija ti a gbo wipe awon Olopa rigba lowo je, oke kan Kumo, Kondo Onirin, Aluki elegun, ti nwon ri gba kuro lowo awon enia dudu na.

## Ilu Gesi gba Ogagun De Gaulle lalejo



Eniti e nwo aworan re loke yi ni Ogagun Charles De Gaulle Olori ilu Faranse ninu keke elesin pelu Obabirin Elizabeth keji ti ilu gesi, won ya aworan yi nigbati Ogagun de gaulle lo se ibewo lo si ilu Gesi ni lolo yi.

Gesi ko fi enu kan oro nipa isetan Ogagun de Gaulle lati pa gbogbo enia Afrika run nipa didan etu Oloro (Atom wo ni ile Sahara ni Afrika. Eyi fiban wa pe a ni lati mo awon oro wa.

